Ìtakora Ẹ̀sìn Nínú Àṣàyàn Fíìmù Yorùbá Adálórí-Ẹ̀sìn-Ìsìláàmù

Halima Omolara, Akinbode
Department of Yoruba, School of Languages,
Sikiru Adetona College of Education, Science and Technology, Omu-Ajose, Ogun State

Àṣamọ̀

Fíìmù jẹ́ ọ̀kan nínú iṣẹ́-ọnà tí àwọn Yorùbá ń lò láti ṣe àtúnṣe àti àfọ̀mọ́ àwùjọ wọn lóde-òní, nítorí pé ọ̀rọ̀ nípa àwùjọ kò lè ṣe aláìjẹ́yọ nínú fíìmù, gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka lítírésọ̀. Ṣùgbọ́n ṣá, púpọ̀ iṣẹ́-ìwádìí tí àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí fíìmù Yorùbá dá lórí àṣà, ìṣẹ̀dálẹ́, ẹ̀sìn ìbílẹ̀, orò àti ẹ̀wà lítírésọ̀ alohùn nínú fíìmù Yorùbá. Ìwádìí ò tíì fi bẹ́ẹ̀ rinlẹ̀ lórí lílo fíìmù gẹ́gẹ́ bí àwòjíjí oríṣiríṣi ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, nínú èyí tí ìtakora ẹ̀sìn jẹ́ ọ̀kan, pàápàá nínú àwọn fíìmù Yorùbá adálórí-ẹ̀sìn-ìsìláàmù. Nítórí náà, ìwádìí yìí ṣe àmúlò tíọ́rì ìfojú-Ìmọ̀-Ìbára-eni-gbépọ̀-wo-Lítírésọ̀ láti ṣe ìtúpalẹ̀ ìjẹ́yọ ìtakora ẹ̀sìn nínú àṣàyàn fíìmù Yorùbá mẹ́rin adálórí-ẹ̀sìn-ìsìláàmù. Àwọn fíìmù Yorùbá tí a mọ̀mọ̀ yàn fún àtúpalẹ̀ yìí ni – Wòsíkẹnkẹ; Ẹ̀sìn Mi; Semiat àti Àdìjátù-Kúbúrà. Ninu àwọn fíìmù yìí ni a ti ṣe àfàyọ kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́ ìtakora ẹ̀sìn tí a sì lo tíọ́rì ìfojú-Ìmọ̀-Ìbára-eni-gbépọ̀-wo-Lítírésọ̀ ṣe àtúpalẹ̀ ìbáyémú wọn ní ìbámu pẹ̀lú ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́ọ́lọ́ọ́ yìí ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ojútùú sí ìtakora ẹ̀sìn gẹ́gẹ́ bí àwọn fíìmù tí a yàn ṣe gbé e kalẹ̀ jẹ́ ẹ̀kọ́ pàtàkì fún àwùjọ wa, èyí tí ó ṣe atọ́kùn fún ìmọ̀ràn tí a tẹ́ pẹ̀pẹ̀ rẹ̀ ní ṣíṣe àgbálọgbábọ̀.

Ọ̀rọ̀ Ìperí: Fíìmù Yorùbá; Ìtakora ẹ̀sìn; Ẹ̀sìn Ìsìláàmù; Ẹ̀sìn Ọmọleyìn-Jésù; Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀; Ìbágbépọ̀ Àwùjọ

Ìfáárà

Ipa kékeré kọ ni fíìmù Yorùbá ń kó ní àwùjọ. Ó wà láti ṣe àtúnṣe sí àwọn ìṣòro tí ó wà nínú àwùjọ. Àwọn òǹkọ̀tàn fíìmù máa ń ṣe àmúlò ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ lóríṣiríṣi gẹ́gẹ́ bí ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún ìtàn wọn. Awòjìji tàbí díígí tí a fi ń wo ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni fíìmù jẹ. Ohun tí a fi gbà pé àwòrán àwùjọ ni fíìmù jẹ ni pé, kò sí ohun tí ó wà nínú àwùjọ tí kò lè fi ara hàn nínú fíìmù tí ó jáde láti inú irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Kódà, ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbàsókè fíìmù Yorùbá kò sé lórí ìdàgbàsókè tó ti dé bá àwùjọ Yorùbá. Àwọn onímọ̀ fẹnukò pé ìdàgbàsókè tó dé bá ìṣèré eégún aláre (Adedeji, 1969, 1981; Akinsola, 2023, 2024) ló dí eré oníṣe onílànà ogúndé títí tí ó fi di fíìmù àgbéléwò (Adeleke, 1995; Adeniyi, 2009; Adagbada, 2010; Alamu, 2010; Adeyinka àti Akinsola, 2016; Akinsola 2020a, 2020b).

Láti ìgbà tí fíìmù Yorùbá ti bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àgbéjádé fíìmù *Àjàní Ògún* ní ọdún 1976 (Alamu, 1991; Adagbada, 2005; Ogundeji, 2014; Akinsola ati Ilesanmi, 2018), onírúurú ni àwọn fíìmù tí ó ti ń jáde ní èdè Yorùbá. Àwọn onímọ̀ sì ti ṣiṣẹ́ lórí ìpínsísọ̀rí àwọn fíìmù Yorùbá wọnyí (Ekwuazi, 1984). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ kan gbà pé kókó-ọ̀rọ̀ kò ṣe é gbára lé láti ṣe ìpínsísọ̀rí fíìmù Yorùbá nítorí ìwọnúbọ̀nú tó peléke (Akinsola ati Adeyinka, 2020), púpọ̀ àwọn onímọ̀ fíìmù àti lítírésọ̀ Yorùbá ló ti lọ òṣùwọn yìí láti ṣe iṣẹ́ ìpínsísọ̀rí yìí. Àwọn ìsọ̀rí tí wọ́n ti pín fíìmù Yorùbá sí ní fíìmù adálórí-ìfẹ́, fíìmù adálórí ọ̀rọ̀ òṣèlú, fíìmù adálórí ìtàn, fíìmù adálórí ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, fíìmù adálórí ìwà ọ̀daràn, fíìmù adálórí ọ̀tẹ̀lẹ́múyẹ́, fíìmù apanilẹ́rìn-ín, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (Adeleke, 1995; Alamu, 2002; Alamu, 2010; Adagbada, 2010). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a gbà pé ìwọnúbọ̀nú kókó-ọ̀rọ̀ lè wà nínú àwọn fíìmù Yorùbá ní ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan, ìpínsísọ̀rí yìí ṣe é gbára lé bí a bá lo olú kókó-ọ̀rọ̀ inú fíìmù náà, pàápàá jùlọ ní ti àwọn fíìmù adálórí ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn tí pépà yìí yàn láàyò.

Ní òde-òní, ọwọ́jà fíìmù agbéléwò Yorùbá ti tẹ̀ síwájú gidi, abe àsíá *Nollywood,* ìyen àgbárijọpọ̀ àwọn òǹṣefíìmù orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni wọ́n wà. Ìwádìí fi hàn pé àjọ àgbáyé nnì UNESCO sọ pé orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni ó wà ni ipò kejì láàrín àwọn onṣefíìmù ní àgbáyé (UNESCO, 2018). Àwọn fíìmù tí àwọn òǹṣefíìmù *Nollywood* Yorùbá ń gbé jáde ń ṣe àkóónú kókó-ọ̀rọ̀ onírúurú láàrín àwùjọ èyí ti ọ̀rọ̀ ajemọ́-Ẹ̀sìn Ìsìláàmù àti ti àṣà ìlo Lárúbáwá gùnlé. A tún ri òbítíbitì àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá ti ń ṣe àfihàn àṣà ìlo Gẹ̀ẹ̀sì, China àti àwọn ìlú mìíràn ní àgbáyé. Èyí wà lára òṣùwọn tí àjọ UNESEO wò mọ́ *Nollywood* lára, tí wọn fi tò ó sí ìpò Kejì láàrin àwon òǹṣefíìmù àgbáyé, (UNESEO, 2018).

Gbogbo àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá, yálà èyí tí ó jẹ ìtàn inú ìwé eré-onítàn kan tí a sọ di fíìmù àgbéléwò ni, tàbí èyí ti òǹkọ̀tàn fíìmù náà pilọ kọ funra rọ ni ó máa ń ní ìwúlò pàtàkì láàrin àwújọ. Wọn sì máa ń jáde pelú èròngbà láti kọ àwùjọ ni ẹ̀kọ́ kan tàbí òmíràn. Onírúurú ọ̀nà si ni òǹkọ̀tàn máa ń gbà gbé eré wọn kalẹ̀. Ò lè wù ú kí ó ṣe é ni ìtàn ayé àtijọ pọnbélé (tí ó fi àtinúdá gbé kalẹ̀), ó sì lè jẹ àwọn ìtàn ìgbàlódé ní yóò dá lé lórí. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, òǹkọ̀tàn lè hun ìtàn ayé àtijọ àti tí òde-òní papọ̀ láti di odidi. Gbogbo àwùjọ ni àwọn ènìyàn ti ni oríṣiiríṣi Ẹ̀sìn ti wọn ń sìn. Gbogbo Ẹ̀sìn ni ó sì máa ń kìlọ ìwà, nítorí ìgbàgbọ́ wọn pé èrè wà fún ìwà yòówu ti ẹ̀dá bá ń hù ni rere tàbí ni bùburú. Ẹ̀sìn tó wà nínú àwùjọ Yorùbá pọ, ṣùgbọn meta pàtàkì ni ó gbajúmọ. Àwọn meta náà ni Ẹ̀sìn Ìsìláàmù, Ẹ̀sìn Ọmọleyìn-Jésù àti Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀. Ẹ̀sìn metọọta ti a menu bà wọnyí tún pín yẹ́lẹ́yẹlẹ́. Àìmọye ìlànà ni àwọn Ọmọleyìn-Jésù ń gbà ṣe Ẹ̀sìn wọn ní onírúurú ilé ìjọsìn bí *Redeem, Celestial, Cherubim and Seraphim, Christ Apostolic Church* àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Ní ti àwọn elesìn Ìsìláàmù náà, a rí àwọn ẹ̀yà ilé ìjọsìn bí *Nasfat, Quoreeb, Tijanniyyat, Quadriyyat, Ahammadiyyah* àti àwọn mìíràn. Bákan náà ni oríṣìí àwọn Ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá náà wà. Lára wọn ni bíbọ

Sàngó, Èṣù, Ọya, Ọsun, Ògún, àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. A tún rí àwọn Ẹ̀sìn àtòkèèrè wá mìíràn ti wọn yàtọ̀ sí Ìsìláàmù, ìbílẹ̀ àti Ọmọleyìn-Jésù. Lára irú wọn ni *Eckankar, Budhism* àti àwọn mìíràn. Bẹ́ẹ̀ àwùjọ kan náà ni gbogbo àwọn olùsìn ẹ̀sìn wọ̀nyí jọ ń gbé. Báwo ni ìbagbépọ̀ wọn ṣe ń rọrùn? Ǹjẹ́ ìtakora ẹ̀sìn ń wáyé? Báwo ni wọ́n ṣe ń wá ojútùú sí ìtakora ẹ̀sìn nígbà tí ó bá ṣẹlẹ̀? Ẹ̀kọ́ wo ni ó yẹ kí a kọ́ fún ọjọ́ iwájú? Gbogbo àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ni pépà yìí wá ìdáhùn sí nípasẹ̀ ṣíṣe àtúpalẹ̀ àwọn àsàyàn fíìmù Yorùbá adálórí-ẹ̀sìn ìsìláàmù.

Fíìmù Ẹ̀sìn wọlé si agódo fíìmù Yorùbá láti lè kọ àwọn òǹwòran nípa Ẹ̀sìn yálà Ẹ̀sìn ìgbàgbọ́ (Kìrísìteenì), Ìsìláàmú àti Ẹ̀sìn ìbílẹ̀ (Kareem, 2015). Èròǹgbà àwọn tí ó ń gbé irúfẹ̀ fíìmù yìí síta ni pé ènìyàn gbọdọ̀ ní Ẹ̀sìn tí yóò máa sìn tí yóò sì ní ìgbàgbọ́ gidi nínú rẹ̀. Irúfẹ̀ àwọn fíìmù náà ni *Semiat, Wòsík*ẹnkẹ, *Ẹ̀sìn Mi, Adijat Kúburà, Ègún Ìpilọ̀ṣọ́, Agbára ńlá, Idà Èṣù, Àṣìṣe ńlá, Ogun Àtelẹ́wá* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn fíìmù ajemesìn yìí ni wọn máa ń dá àwọn oníṣe ibi ni ẹ̀bi, tí wọn sì máa ń fi ire fún àwọn tí wọn ń sin Olọrun bó ti yẹ.

Àkíyèsí ti a ṣe nípa àwọn fíìmù àgbèléwò Yorùbá lápapọ̀ ni ó mú wà ṣíṣe lórí àwọn àṣàyàn fíìmù tì ó je mọ ti Ìsìláàmù. Ìdí ni pé, púpọ̀ nínú àwọn ènìyàn kò kọbíara sí ọnà ti àwọn fíìmù ń gbà kọni lekọọ ìwà, léte àtimú ètò ìbára-eni-gbé-pọ̀ tí ó lóòrìn wọ inú àwùjọ wa, kí ó sì dín ìtakora ẹ̀sìn kù. Ìdí nìyí tí a fi yan ìtakora ẹ̀sìn nínú àwọn fíìmù a- dá-lòrí-Ẹ̀sìn Ìsìláàmù láàyò. A gbìyànjú láti ṣe àyẹ̀wò bóyá wọn wúlò fún àwùjọ, pàápàá nínú ètò ìbágbépọ̀ láàrín àwùjọ. Ohun tí ó jẹ wà lógún nínú iṣe ìwádìí yìí ni àyẹ̀wò ìtakora ẹ̀sìn tí ó ṣú yọ nínú àwọn fíìmù a- dá-lórí Ẹ̀sìn Ìsìláàmù ti a yàn láàyò, làti lè sọ ní pàtó, irú iṣe tí àwọn òǹṣefíìmù ń fi àwọn fíìmù náà rán sí àwùjọ.

Fíìmù elédè Yorùbá a-dá-lórí-esìn Ìsìláàmù máa ń pe àkíyèsí àwọn ènìyàn àwùjọ sí orísiiríṣi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọn kò kọbiara sí, tí ó wà nínú esìn Ìsìláàmù, tí òǹkọtàn fíìmù máa ń gbé wọ àwọn **a sín Ẹ̀sìn je** nínú fíìmù láti bu enu àte lu àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kọọkan tí ó sì ń wáyé láwùjọ. Bí ọjọ ṣe ń gorí ọjọ, tósù ń gorí osù, tí ọdún náà ń lé kùn sí i, bee náà ni fíìmù àgbéléwò Yorùbá ń gbèrú si i. Èyí kò yani lenu, nítorí kò sí ohun tí ó dúró sí ojú kan ṣoṣo. Ayé ìjọsí ni tíátá agbéréká gbayi, tí ó jẹ ohun àkọtun lójú àwọn ènìyàn ìgbà náà. Nígbà ti ó tún ṣe, tíátà tún di ohun tí á ń wò ní inú ilé sinnimá. Bẹ́ẹ̀ ni ìgbà tún yí padà, ayé dayé àgbélé-wò-eré; ó dayé fíìmù àgbéléwò. Ọkan pàtàkì lára èròjà inú lítíréṣọ́ lábe eré-oníṣe ni fíìmù jẹ. Ìdí nìyí, ti ọrọ́ fíìmù gan-an fi jọjú gege bí èyí tí a lè fi ṣe àwòjíji àwùjọ wa. Fún ìdí èyí, a yan àwọn fíìmù àgbéléwò merin ọtọọtọ́ láàyò. Àwọn fíìmù merẹ́ẹ̀rin (*Wòsík*ẹnkẹ*; Ẹ̀sìn Mi; Semiat àti Àdìjátù-Kúbúrà)* tí a yàn láàyò jẹ èyí tó jẹ mọ Ẹ̀sìn Ìsìláàmù. Ohun tí a ní lọkàn gan-an lórí èyí ni pé, a fi ṣe àyọwò bí Ẹ̀sìn Ìsìláàmù ti rí nínú àwùjọ Yorùbá. Ìdí ni pé, àwọn Yorùbá ti wọn ṣe Ẹ̀sìn Ìsìláàmù gan-an ni àwòràn wọn fi ara hàn nínú àwọn fíìmù àgbéléwò mẹ́ẹ̀rẹ̀rin ti a yàn láàyò. Èdè Yorùbá ni àwọn akópa inú àwọn fíìmù náà sọ jù lọ. Fún ìdí èyí, a ka àwọn fíìmù ti a lò bi òdiwọn ìwádìí wa yìí kún àpeere àwọn fíìmù Yorùbá tí ó jẹ mọ Ẹ̀sìn Ìsìláàmù.

Tíọrì Àmúlò

Ìfojú-Ìmọ̀-Ìbára-eni-gbépọ̀-wo-Lítíréṣọ́

Ọnà méjì ni a lè pín àwọn onímọ̀ tíọrì yìí sí. Àwọn tí wọn wà ni ìsọrí kìn-ín-ni ni wọn rí lítíréṣọ́ gege bí àwòjìjì àwùjọ. Ọkan lára àwọn ti wọn kọkọ gbé tíọrì yìí láruge ni orúkọ rọ ń jẹ Louis de Bonald (1754-1840). Ìwádìí tí Laurenson àti Swingewood (1971) ṣe lórí tíọrì yìí láàrin ọdún 1970 sí ọdún 2000 ṣe àfihàn Louis de Bonald gege bí onímọ abala tíọrì Ìfojú-ìmọ̀-ìbára-eni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ́ tí ó gbà pé díígí àwùjọ ni lítíréṣọ́ jẹ. Ohun tí àwọn lámèétọ yìí tenu mọ ni pé, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni ó máa ń hàn nínú lítíréṣọ́, wọn gbà pé, ó pọn dandan kí lámèétọ ṣe ìwádìí fínnífínní lòrí ìṣẹ̀lẹ̀ inú lítíréṣọ́ bí ó tí bá ojú ayé mu tàárà. Lójú àwọn agbáterù abala yìí, ìṣẹ̀lẹ̀ inú lítíréṣọ́ jẹ èyí tí ó bá ojú ayé mu. Wọn ni, lámèétọ gbọdọ̀ lè ṣe àfihàn àwọn ìjọra ni onírùurú àwùjọ àti ìdí tí ìjọra yìí fi wà. Wọn pè é ni "mirror image approach", èyí tí a lé pè ni "ìlànà àfihàn bí-ọrọ́-ṣe-rí-gan an". Louis de Bonald (1754-1840) ṣàlàyé pé "Through a careful reading of any nation's literature, one could tell what his people has been". (Nípa kíka lítíréṣọ́ orílọ-èdè kan fínnífínní, a lè sọ bí ìgbé-ayé àwọn ènìyàn náà ṣe rí látọyìnwá). Ohun tí de Bonald (1754-1840) wí ni pé, bí a bá ka lítíréṣọ́ èyíkéyí tí ó jáde láti inú àwùjọ kan dáadáa, a ó lè sọ nípa àṣà, Ẹ̀sìn àti ìṣe wọn láti ìgbà ìwáṣọ àti àwọn àyípadà tí ó ń dé bá àwùjọ beọ. Halsey (2004:153) náà ṣàlàyé pé :

> Through fact gathering with a desire to arrive at coherent generalizations about significant social behaviour marked the beginning of sociology.
> (Síṣe àkójọpọ̀ ìwádìí òtitọ́ tó jinlọ pelú èròǹgbà láti gúnlọ lórí ohun tí ó dájú nípa àwọn ìhùwàsí láàárín àwùjọ èyí tó ṣe déedée pelú gbogbo ènìyàn, ló bọrọ ìmọ ìbára-eni-gbépọ̀).

Ohun tí àwọn onímọ wọnyí ń sọ ni pé, dandan ni kí nǹkan kan gbòógí wá tí yòó so àwùjọ papọ̀. Bí a bá wá wo irúfẹ̀ àwùjọ Áfíríkà tí lítíréṣọ́ alohùn ti gbilọ ju tí àpilọkọ lọ, a ó rí pé èrò àwọn onímọ yìí ṣe dédedé nípa ìtumọ tí a lè fún lítíréṣọ́ nípa fifi ṣe àwójiji àwùjọ. Àwọn ewí alohùn, eré-oníṣe àti ìtàn -àròsọ ọlọrọ geere tí a máa ń lò, jẹ àgbékalọ àwọn àgbàágbà ti wọn mọ nípa ìtàn-ìwàsọ,

ìtàn àpilọkọ àti àwọn ìtàn-àròsọ tó ṣe wekù pelú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ wọn. Fún ìdí èyí, a lè sọ pé, àkóónú àlọ pípa nínú àwùjọ Yorùbá ń tọka sí àwọn onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó lè jẹ ìtàn-ìwàṣọ tàbí ìtàn akọní, ó sì lè jẹ ìtàn orírun ìlù. Bí a bá tilọ kíyèsí ohun tí Babalọlá (1966: 7) sọ nípa ìtumọ lítíréṣọ, à lé fi ìdí rọ múlọ pé lóòótọ ni ò máa ń ya àwòràn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ tàárà. Babalọlá (1966: 7) sọ pé :

> Lítíréṣọ ni àkójọpọ ìjìnlọ ọrọ ni èdè kan tàbí òmíràn, ìjìnlọ ọrọ tí ó jásí ewì, àròfọ ìtàn, àlọ, ìyànjú, ìròhìn, tàbí eré-onítàn, eré akọnilọgbọn lórí ìtàgé, kò sì tò di ọrọ kikọ sílọ àti titọ jáde nínú ìwé, lítíréṣọ lè wà nínú ọpọlọ orí àwọn ọmọràn.

Ohun tí Babalọlá (1966:7) fi yé wa ní pé, àwọn lítíréṣọ tí ó wà ni kìkọ sílọ ní inú ìwé jẹ àwọn tí àgbékalọ wọn àkọkọ jẹ èyí tó máa ń wà nínú ọpọlọ orí àwọn onímọ lítíréṣọ, ṣùgbọn, ó ṣòro díọ láti lè mọ ohun tí ń be nínú ọpọlọ láìjẹ pé a gbè wọn kalọ lójú agbo eré. Bí a bá wá fi èrò àwọn onímọ ìfojú-ìmọ-ìbágbépọ-wo lítíréṣọ yìí wò ó, a jẹ pé ìrírí àwọn agbàágbà inú àwùjọ tí wọn jẹ àgbáterù àwọn lítíréṣọ alohùn náà ni ó wà nínú ọpọlọ wọn (Adeyemi, 2006). Àwọn ọwọ kejì nínú tíọrì Soṣiọlọjì lítíréṣọ tí a ṣe ni ìfojú-ìmọ-ìbára-eni-gbé-pọ-wo-lítíréṣọ gbájú mọ ipa ti àwùjọ kọọkan ni lórí lítíréṣọ.

Hippolyte Taine (1828-1893) nínú Oyèdéjì (2002:3) sọ pé ọmọ il2 Faransé ni Taine òun ló dábàá orúkọ "Sociology of Literature". Ohun tí ó je tíọrì yìí lógún ni wíwo àjọṣepọ tó wà láàrin àwùjọ àti eni tí ó ń ṣe iṣe-ọnà ní àwùjọ.Tíọrì ìfojú-ìmọ-ìbára-eni-gbé-pọ-wo-lítíréṣọ je ìmọ nípa ọdá ni àwùjọ ní pàtàkì jùlọ lórí àṣà àti iṣe rọ ní àwùjọ èyí tí a wà gbé gba ìlànà sáyeńsì.

Tíọrì ìfojú-ìmọ-ìbára-eni-gbé-pọ-wo-lítíréṣọ máa ń pe àkíyèsí wa sí èrò ọrọ-ajé, èrò ìṣèlú àti èrò Ẹ̀sìn ní àwùjọ. Àwùjọ àti lítíréṣọ kò ṣée yà sọtọ síra wọn, inú àwùjọ ni a ti ń ṣe àtòpọ àwọn kọkọ-ọrọ tí à ń sọ di lítíréṣọ. Èyí hàn kedere nínú èrò Ògúnṣínà (1987:19) tó sọ pé:

> Literature is concerned with man and his society. It is an art e composed of words in such a way that it proffers entertainment, enlightenment and relaxation.
> (Lítíréṣọ je mọ ènìyàn àti àwùjọ rọ. Ó jẹ iṣe-ọnà ti a hunpọ nípasọ ọrọ ni ọnà tí ó ń pani lerìn-ín, tí ó ń kọni lekọọ, tí ó sì ń mú kí á gbádùn ara eni).

Àkíyésí Ogunṣínà (1987:19) yìí bá lítíréṣọ alohùn àwùjọ Yorùbá mu, ó sí bá àwọn lítíréṣọ àpilọkọ yòókú mu káàkiri àgbáyé. Onímọ yìí fi yé wa pé lítíréṣọ àti àwọn ọdá ènìyàn jọ ń rìn papọ nínú àwùjọ ni. Fún ìdí èyí, a lé gbà pé kò sí àwùjọ tí kò ní lítíréṣọ tirọ. Bí àwọn ènìyàn inú àwùjọ kan bá ń gbéra kúrò nínú àwùjọ wọn lọ sí àwùjọ mìíràn, wọn a máa mú lítíréṣọ wọn lọwọ. Ìdí nìyí ti Ogúnṣínà (1987:19) fi gbà pé ibi tí a bá ti rí àwùjọ àwọn ènìyàn, a máa ń rí lítíréṣọ wọn níbọ. Ogúnṣínà (1987:19) tilọ fi yé wa pé, laáríjá lítíréṣọ ni ìdánilekọọ, ìdánilárayá àti igbáfe. A lè fi kún un pé, lítíréṣọ máa ń ṣe àfihàn àṣà àti iṣe àwùjọ rọ lọlọkan-ó-jọkan, ó tún máa ń ṣe àfihàn gbogbo èrò yóòwù ti ó bá wáyé nínú irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Àwọn olùṣẹ̀dá lítíréṣọ máa ń lò ìrírí wọn nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ wọn láti ṣe àgbékalọ lítíréṣọ. Bí lítíréṣọ bá jẹ ìfojú-eni-hàn, tí àwùjọ si ṣe àkóónú gbogbo èrò ìgbé-ayé àwọn ènìyàn, a jẹ pé, kó si ohun tó ṣelọ nínú àwùjọ tí a kò lé bá pàdé nínú lítíréṣọ. Ìbáṣepọ àwọn ènìyàn gan-an ni olúborí èrò ìgbé ayé wọn. Fún ìdí èyí, bí a bá ń sọ nípa èrò-ìṣèlú, èrò ọrọ-ajé, èrò-amúlùúdún àti Ẹ̀sìn àwújọ kọọkan, inú èrò-ìbágbépọ wọn ló pọkun sí. Ìdí ni pé, ìbáṣepọ àti àjùmọrin ìwà ni ìbáṣepọ tùmọ sí. Ìbáṣepọ tayọ àjọgbépọ nínú ilé tàbí nínú àwùjọ nìkan, ó kan kí a máa tọka sí gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tó rọ mọ àjọṣepọ àwọn ènìyàn nínú àwùjọ.

Tíọrì tí a yàn láàyò fún ìtúpalẹ̀ ìtakora ẹ̀sìn fún àmúgbòòrò ìbára-eni-gbé-pọ nínú àṣàyàn fíìmù elédè Yorùbá a-dá-lórí-Ẹ̀sìn Ìsìláámù ni Ìfojú-ìmọ-ìbára-eni-gbépọ-wò-lítíréṣọ. Ní pàtò, Ìfojú-ìmọ-ìbára-eni-gbépọ-wo-lítíréṣọ ń ṣe àfihàn àṣà, Ẹ̀sìn, ìtàn, èrò-ìjìnlẹ̀ àti ojú-àmúwayé àwọn ènìyàn inú àwùjọ tó ni lítíréṣọ ti a lò ó fún (Abrams, 1981).

Ìsọnisókí Àwọn Fíìmù Mereerin tí a yàn láàyò

Àwọn fíìmù merin otooto tí a lo àkóónú wọn ní fíìmù ajemọ-esin, ni a yàn láàyò. Àwọn náà ni *Wòsíkẹnkẹ; Ẹ̀sìn Mi; Semiat àti Àdìjátù-Kúbúrà.* Àkọlé ti wọn fún àwọn fíìmù náà wà ni ìbámu pelú èròǹgbà àwọn òǹkọtàn wọn. Ìdí ni pé, àkọlé wọn tọka sí àṣà àti ìṣe àwọn Mùsùlùmí ti wọn jẹ elesìn Ìsìláàmù. Lọnà àkọkọ, ìlànà orúkọ jíjẹ ti esìn Ìsìláàmù fára hàn nínú àwọn àkọlé wọnyí. Lọnà mìíràn ọwọ, kókó-ìtàn àti àkóónú àwon fíìmù náà ló bí orúkọ wọn. Ẹ jẹ kí á wo ìsọnísókí wọn láti ri òkodoro ohun tí à ń wí yìí.

Wòsíkẹnkẹ

Iṣe awakọ èrò ní ibùdókọ ni bàbá Wòsílàt ń ṣe. Onísùúrú ọdá tí kò láápọn ni bàbá Wòsílàt jẹ. Sùúrù rọ yìí a si máa ṣe àkóbá fún un ní ibùdókọ èrò tì ó ń ṣe iṣe. Àwọn akegbe re tí wọn jẹ oníwà jágídíjàgan máa ń re e je, èyí tí ó ń ṣe àfihàn pé àlááfíà re ó lè ṣe okùnfà ìtesíwájú kò sí láàrin àwọn òṣìṣe inú ibùdókọ náà. Èyí ló mú kí Wòsílàt ọmọ re di ọmọ ìbùdòkọ láti máa kọ ìyà fún bàbá re. Àlùbami ni Wòsílàt máa ń lu àwọn tó bá kọjú ìjà sí i ní ibùdókọ. Ọrọ re gan-an wá sú bàbá rọ tí ó jẹ olùfe àlááfíà, ó sì gbà á nímọràn láti padà sí ilé-ekọ rọ. Wòsílàt fárígá fún bàbá re pé òun kò lọ sí ilé-ọkọ, pé

àwọn kò tí ì lè bere iṣe kankan ni ilé-ekọ àwọn. Ó ya bàbá Wòsílàt lenu pé, kí ni ó lè fà á tí ọmọ òun fi takú pé òun kò lọ sí ilé-ekọ ? Éyí ló mú un ronú pé, bóyá owó tí Wòsílàt ń rí ni ibùdókọ ló ti fe mọ ọn lójú, tí kò fi fe lọ sí ilé-ekọ mọ. Yorùbá bọ, wọn ni àròkàn ní í fa ekún àsun-ùn-dá. Ẹrù ohun tó ṣe okùnfà bí bàbá Wòsílàt ṣe di awakọ ló ń bà á, tí ó fi ń fi ọwọ líle mú àwọn ọmọ re láti ka ìwé. Òṣìṣe ìjọba ni bàbá Wòsílàt nígbà tí ó wà ni ọdọlangba. Ìdí iṣe to ń ṣe ni ó ti ko àgbakó esùn olé jíja. Wọn rán an ni ewọn nítorí ọràn ti kò mọwọ-mọ-esọ re. Èyí ló sọ ọ di awakọ erò nígbà tí ó jáde nínú ewọn náà. Bàbá Wòsílàt pinnu láti ni ìgbekelé nínú Olọrun, nítorí ohun ti ó ṣele sí i tí ò fi di èrò ewọn. Ẹrí ọkàn ń jẹ ẹ pé àinígbekelé nínú Olọrun àti àìsìn Olọrun bí ó ti tọ ni àjálù náà fi ṣele sì òun. Ó gbàgbọ pé ó wu Ọlọrún láti kọ òun ni ọkọ nì ó fi yọ òun kúrò nínú ewọn. Ìfe ló da Ọláṣení àti Wòsílàt pọ, tí Ìyá Ọláṣení sì kọ pé wọn ko gbọdọ fe ara wọn. Kerekere, ọrọ náà dé ọdọ bàbá Wòsílàt. Inú bí bàbá Wòsílàt nígbà tí ó gbọ sí ọrọ náà, ó sì pa ìtàn fún ìyá Ọláṣení láti rán an létí àjọṣepọ tó wà láàrin òun àti ọkọ re lenu ise Ìjọba tí ó gbé òun dé ewọn. Nígbà tí ìyá Ọláṣení gbọ itàn àgbọfìdíjanle yìí, òógùn ṣi yọ lára re, nítorí kò dá bàbá Wòsílát mọ mọ. Kó dúró fésì si gbogbo ohun tí bàbá Wòsílàt sọ náà, ilé ló gbà lọ láti lọ ròyìn gbogbo ohun tí ó gbọ fún ọkọ rọ. Bí bàbá Oláṣení ti gbọ ìtàn náà lenu aya re, ó pe aya re pé kí ó jẹ kí àwọn lọ tọrọ ìdáríjì lọdọ bàbá Wòsílàt, láti lè jẹ kí àjọṣepọ tí ó dára wà láàrin ebí méjèèjì, kí àwọn sì gbà kí ọmọ wọn Oláṣení fe Wòsílàt ọmọ re. Oro kò rí bí bàbá Oláṣení ti rò, nítorí bàbá Wósìlàt fárí gá pé òun kò le gbà kì ọmọ òun fe Ọláṣení, nítorí pé òun ti pinnu pé òun kò ní bá wọn ná nínú owó eje wọn. Ibi tí ọrọ náà parí sí dun Oláṣení púpọ, nítorí ko mọ orísun ọrọ bàbá re. Ó bínú jáde kúrò nínú ilé bàbá re, eré sì parí.

Ẹ̀sìn Mi

Nínú fìimù *Ẹ̀sìn Mi yìí,* wọn ṣe àfihàn ọmọbìnrin kan tí orúkọ rọ ń jẹ Kádíjá àti ọrọ Barakat tì ń sin esìn omọleyìn-Jésù. Ọ̀rẹ̀ kòríkòsún ni Kádíjá àti ọrọ re tí ń ó jẹ Ọmọleyìn-Jésù yìí. Wọn a jọ máa sin ara won lọ sí ilé ìj-sìn wọn, Kádíjá sín ọ̀rẹ̀ rẹ̀ lọ sí ṣọ́ọ́ṣì pelú ìjáàbù lórí láìbìkítà ojú tí àwọn ènìyàn yóò máa fi wo òun. Èyí ya arákùnrin kan tí ó pàdé wọn lenu, tí ó fi gbé òṣùbá fún wọn. Ọkùnrin náà ya àwórán àwọn méjèèjì sí orí erọ-alágbèéká rọ. Ọudus egbọn Kádíjá gbe erọ-alágbèéká àbùró re, ó ń wo fídiò tí àbúrò re ti ń wò kí ó tó wọọlé. Àwòrán Rọmọlá àti ìpede enu re ti Ọudus ri nínú fídiò náà ló mú ni ife re, ara Ọudus kò tilẹ̀ balẹ̀ mọ́, láti ìgbà tó rí àwòrán Rọ̀mọ́lá lórí fídiò. Nígbà àbúrò Ọudus wọlé dé láti ibi ti ó ti lọ ra káàdì-ìpè orí ọrọ-alágbèéká, ó bá a sọ edùn ọkàn re nípa Rọmọlá. Ò bèèrè orúkọ ọmọbìnrin náà lọwọ àbúrò re, ó sì lọ ṣe àyewọ re lórí ero-ayélujára. Oro esìn tí Ọudus gbọ lenu Rọmọlá wọ ọ ni akínyọmí ara, ó sì wà wọrokọ ṣàdá. Ọudus pa ir- fún Rọmọlá pé òun kì i kírun, bí ó tile jẹ pé ilé esìn Ìsìláàmù ni wọn bí òun sí. Ó jẹje e fún Rọmọlá pé òun ṣetán láti máa bá a sin esìn omọleyìn-Jésù tí ó ń sìn náà. Inú Rọmọlá dùn nígbà tí ó gbọ eje tí Ọudus jẹ fún-un, ó sì mú Ọudus lọ sí ọdọ alàgbà Ìjọ re, wọn ṣe ìrìbọmi fún un gege bí ọmọleyìn-Jésù. Wọn yí orúkọ Ọudus padà sí *Micheal*, òun náà sì pinnu láti mú Rọmọlá lọ sí ọdọ àwọn òbí rẹ̀, nígbẹ̀yìn, wọn padà fe ara wọn. Nígbà tí gbegede fe gbiná nínú ilé láàrín Rọmọlá àti Ọudus, Rọmọlá ká ọkọ re mọ ibi tí ó ti ń kí ìrun lọjọ kan. Ọudus pa iro fún ìyàwó re pé iṣe Èṣù ni, pé kí ó dáríji òun. Rọmọlá kò jiyàn mọ, wọn sì ń bá ife wọn lọ. Kò pe púpọ, Rọmọlá lóyún fún Ọudus, inú Ọudus sì dùn pé ọwọ òun ti te eèku ìdà. Ọudus wá fárígá fún Rọmọlá pé kò gbọdọ lọ sí ilé ìjẸ̀sìn tí ó ń lọ mọ, pé ìrun ni yóò máa kí. Èyí jẹ kàyéèfì fún Rọ̀mọ́lá, ó sì takú pé òun kò lè kí ìrun. Orí ifànfà yìí ni wọn wà, tí Ọudus kò tile fi irun kíkí bò fún aya re nínú ilé mọ. Rọmọlá kò bèṣù bọ̀pẹ̀, ó lọ kó gbogbo ohun tí Ọudus ọkọ re fi ń kírun pamọ́. Ọudus ṣe àfẹ́kù Kùránì àti gbogbo àwọn ohun tí ó fi ǹ kirun nìnú ilé, ò sì bèèrè lọwọ ìyàwó re, ìyàwó re derù bà á pé òun ti da iná sun gbogbo àwọn nǹkan ti ọkọ òun ń wá. Ẹrù ba Ọudus, jìnnìjìnnì sì bò ó. Ó wọ ìyewù aya re lọ gbé ìwé Bíbélì tire náà; ó dá iná sun ún. Gọngọ wá sọ nínú ilé láàrín tọkọ taya wọn. Àìgbọra-eni-yé be síle nínú ilé, iná sì ràn. Rọmọlá bínú kó erù jáde lọọdọ Ọudus pelú ègún tì ó gún un fún-un. Rọmọlá kò tí ì rìn jìnàà ti ọsan tí ké lórí Ọudus nínú ilé. Àìsàn ete dà bò ó ni gbogbo ara nítòrí Bíbélì tí ó dá iná sun. Wọ n gbé Ọudus lọ sí ilé ìwòsàn, ara re kò yá. Èyí ló mú kí bàbá Ọudus fi ese ilé tọ ọ láti mọ orísun àìsàn tó dé sí ọmọ re nì ọsán gangan. Àlùfáà tí bàbá Ọudus lọ ṣe ìwádìí lọdọ re fi yé e pé, ọmọ re yájú sí Olọrun nípa ire pípa ni, nítorí náà, wọn níláti wá ìyàwó re rí, kí ó lọ ṣàdùrá fún un ní ilé ìwòsàn. Wọn fi kún un pé Ọudus gbọdọ túúbá lọwọ Ọlọrun. Ọudus toro ìdáríjì ese, aya re náà si ṣe àdúrà fún ún. Ara Ọudus yá, wọn sì so òun àti aya re pọ padà bí ọkọ àti ìyàwó. Rọmọlá jẹje e fún àwọn mọlebí ọkọ re láti máa sin esìn tí ọkọ re ń sìn. Ìfe tuntun sì lale hù láàqrín Rọmọlá àti Ọudus ọkọ re nípase gbígbọ ara wọn yé àti ìfe tí ó padà sí àárín wọn. Rọmọlá gbà láti máa je Áyìṣá gẹ̀gẹ̀ bí orúkọ Ìsàmì fún esìn Ìsìláàmù.

Semiat

Ìyá tí ó bí Semiat ti kú, bàbá re nìkan ló sì ń da gbọ bùkátà re. Bàbá Semiat lówó lọwọ àti àwọn ìléeṣe ńlá ńlá. Bàbá Semiat ni ìfẹ́ ọmọ re kan ṣoṣo náà dé góńgó, tí ó fi jẹ pé kò sí ohun tí kò lè fún ọmọ náà. Ọ̀rọ̀ ìfẹ́ tí bàbá Semiat ní sí yìí ló rán ọrọ ọkọ tí Semiat fe fe. Ọjọ tí Semiat pàdé Segun gege bí ololùfe àkọkọ, àwọn méjèéjì nífe e ara wọn. Ẹ̀sìn omoleyin-Jésù ni Segun ń sìn, tí ó sì tako esìn

Semiat. Semiat kò náání esìn Segun, nítorí ìfe tí ó ni sí i. Ó mú Segun wá sí ọdọ bàbá re láti ṣe àfihàn re gege bí olólùfe òun. Bàbá Semiat béèrè esìn Segun àti ìlú re, nígbà tí Segun sọ pé esìn omoleyin- Jésù ni òun ń sìn, bàbá Semiat fi yé e pé kò lè fe ọmọ òun. Oro náà dun Semiat àti Segun púpọ̀, ṣùgbọn wọn kò ní ìkápá lórí àṣe bàbá Semiat. Àwọn méjèèjì pínyà, oníkálùkù sì bá igbé ayé re lọ. Abdul-Lateef ni àfesọnà kejì tí ó lo ìfe ìtànje pelú Semiat. Ó gbàgbọ́ pé bí òun bá tan Semiat je láti sọ fún un pé òun ṣì ń sin esìn Ìsìláàmù, ànfààní yòó ṣí ṣíle fún òun láti gba iṣe kọngiílátọ tí ó fe gbà lọdọ bàbá Semiat. Ọjọ tí Semiat mú Abdul-Lateef wá sí ọdọ bàbá re láti ṣe àfihàn re gege bí ọkọ àfesọnà re, àṣírí tú lọjọ náà. sàdéédé ni ero Abdul-Lateef dún, tì orin esìn omoleyin-Jésù dún níbe. Èyí kò tile tí i jọ bàbá Semiat lójú, bí kò ṣe àwọn oro tó ń fi etí kọ nígbà tí Abdul-Lateef ń bá eni tó ń pè é sórí ero-alágbèégká re sọro Bàbá Semiat rí i pé elesin omoleyin-Jésù ni Abdul-Lateef tí ó ń pa ire fún àwọn. Inú bí bàbá Semiat, ó sì kọkọ lé ẹlẹ́yọ́rọ́ Abdul-Lateef lọ ná, kí ó tó fàbọ̀ sí ọ̀dọ̀ adìye Semiat ọmọ re. Ọkùnrin onísìnná, ọlọtí àti oníwàkiwà kan ni ore Semiat lọ le ìdí àpò pọ mọ. Ó sọ fún ọkùnrin náà pe, ó gbọdọ yí ìwà re padà sí ti Mùsùlùmí gidi tí ó bá mọ pé òun fe fe Semiat. Lóòótọ, Mùsùlùmí ni Yusuf tí Semiat sese páde yìí, ṣùgbọn kì i kirún déédéé. Yusuf máa ń mu ọtí, ó sì tún máa ń ṣe ṣìná. Gbogbo èyí ni Yusuf ti ọwọ re bọle nígbà tí ó pàdé Semiat. Àwọn méjéèjì jọ ni ife ara wọn. Semiat mú Yusuf lọ sí ọdọ bàbá re láti fi hàn gẹ́gẹ́ bí ọkọ àfesọnà re. Leyìn gbogbo ìwádìí tí bàbá Semiat ṣe, ó rí i pé Mùsùlùmí ni Yusuf lóòótọ, ó sí fi ọwọ sí i.

Àṣírí ìwà àgbérè ṣíṣe, ọtí mímu, sìgá mímú àti àgbo ijó líló tí ó ti mọ Yusuf lára tele tú sí ìyàwó re Semiat lọwọ. Inú bí I, ara re kò gbà á nínú ìlé mọ. Gbogbo ète ti Semiat pa láti dáwọ ìwà náà dúró fún ọkọ re ló já sí pàbo. Fún ìdí èyí, ó pinnu láti kó erù re kúrò lọ sí ilé bàbá re padà. Ó fi ehónú hàn sí bàbá re pé oro esìn ló fi ṣe àkóbá fún òun, tí kò jẹ kí òun fe eni tó wu òun. Bàbá re be e , ó sì ṣe ìwàásún fún un pé kò sí ohun tó lé, tí Ọlọ́run Ọba Àláà kò lè sọ dero, àti pé òun gbàgbọ pé Ọlọ́run máa yanjú ìṣòro re láìpe. Kò pe púpọ̀ Semiat padà sí ọdọ bàbá re, ní ó tí rí i pé òun ti fẹ́ra kù. Ọ̀rọ̀ oyún náa dùn un púpọ̀, ó sì lọ sọ fún bàbá re. Baba Semiat fi òye àgbà àti ìgbàgb- rẹ̀ nínú Ọlọ́run gbé ọ̀rọ̀ oyún náà; pé Ọlọ́run nìkan ni ó yé. Bàbá Semiat ránṣe sí Yusuf láti wá rí òun lórí ọ̀rọ̀ ìyáwó re. Yusuf kọ. Nígbà tí àwọn mọ̀lẹ́bí ọkọ àti ìyàwó pawọ́pọ̀ bá Yusuf wí lórí ọ̀rọ̀ náà, ó jẹ́jẹ́ẹ́ fún wọn pé òun yóò jáwọ ninú gbogbo ìwà burúkú tí òun ń hù, òun yóò sì máa sin Ọlọ́run Ọba Àláà bí ó ti tọ àti bí ó ti ye. Àwọn mọ̀lẹ́bí ọkọ àti íyàwọ yanjú ọ̀rọ̀ fún Yusuf àti aya re Semiat, wọn sì padà ń gbé ìgbé ayọ láàrín ara wọn gẹ́gẹ́ bí Mùsùlùmí òdodo. Eré sì parí.

Adijatu Kubura

Ìṣòro ló dé bá bàbá Adijatu nígbà tí ò di ọsán ọjọ ayé re, kò sì bí ju ọmọ kan ṣoṣo lọ tí ìyàwó re fi kú. Bàbá Adijatu wá di edun arinle gbàá fún àìfe ṣe Ọlọ́run Ọba Àláà. Ìyá olówó tabua kan wà ní àdúgbò bàbá Adijatu tí wọn ń pé ní *Madam* Arówólò. Kò sí ọkúnrin tí ó ní owó tó ìyá náà ni gbogbo agbégbè re. Ìyá yìí wà ni àléébù kan tì kò ṣeé fi yangàn. Àléébù náà ni pé, kò ni àánú enikeni lójú. Bí owó re ti pọ tó, kì í fún enikeni ní owó àyàfi àwọn ọmọ rẹ̀ ọkùnrin àti obìnrin. Okọ obìnrin yìí ti kú, òun àti àwọn ọmọ re méjéèjì ni wọn ń gbádùn ogún ọkọ re, obìnrin yìí a tún máa ṣe òwò àlè. Èyí náà wà lára ohun tí ó ṣe ikú pa ọkọ *Madam* Arówólò. Túnjí ọmọ *Madam* Arówólò tí ó jẹ ọkùnrin ni ife Adijatu, ṣùgbọn gbogbo ìgbìyànjú re láti wá ojúrere ọmọbìnrin náà ló já sí pàbó. Ìyá re pàápàá tilọ ta kò ó láti fe Adijatu nítorí pé ó jẹ ọmọ akúṣee. Láti ìgbà tí àbúrò re obìnrin pàápàá ti mọ pé ọgbọn òun ni ìfe Adijatu ló ti ń fi ojú ọmọbìnrin náà han èèmọ ní àdúgbó. Gbogbo bí ọmọ *Madam* Arówólò ti ń fòòró ọmí Adijatu yìí, ọmọbìnrin náà kò fi ṣe ìbínú. Gbogbo ìgbà ni Adijatu máa ń dá bàbá re lọkàn le pé kí ó ní sùúrù, pé ìgbà sì máa yí padà sí rere fún un. Adijatu sùn lọjọ kan, ó lá àlá pé òun bá ara òun ni abà kékeré kan tí àlùfáà- ńlá kan ń gbé pelú àwọn Ẹlehàá re nìkan ṣoṣo. Ìṣípaya ti wọn fi hàn án lójú àlá náà ni pé Àlùfáà náà yóò fi ọnà han àwọn, tí òun àti bàbá re bá lọ sí ọdọ re. Adijatu ròyìn àlá àti ìṣípayá inú àlá náà fún bàbá re. Nígbeyìn, wọn padà mọ ilé Àlùfáà-ńlá ni ìlú Àdáńlá. Nígbà tí Àlùfáà-ńlá ṣe àyọwò sí ọrọ wọn, ohun tí Ọlọ́run fi yé e ni pé, bàbá Adijatu kò lé ni owó títí yóò fi kúrò láyé.

Ẹrù bá Álùfáà-ńlá lórí oro tì ò gbọ nípa ètò ayé bàbá Adijatu lọdọ {l-run, ó sì lọ sọ tàárà fún bàbá Adijatu bee, inú ìbànújẹ àti ìrònú ni bàbá Adijatu àti ọmọ rẹ̀ bá kúrò ni ọdọ Àlùfáà-ńlá. Àwọn méjéèjì lọ ilé, bí ó tilọ jẹ pé ko tete Adijatu lọrùn ni tire. Adijat padà lọsí ọdọ Àlùfáà-ńlá láì-jẹ kí bàbá rẹ̀ mọ, nígbà tí ó dé, bàbá rẹ̀ bèèrè ibi tí ó lọ, ìyen fi yé e pé ọdọ Àlùfáà-ńlá ni òun lọ láti tún lọ wádìí ọnà àbáyọ sí ìṣòro àwọn.

Adijatu ṣàlàyé fún bàbá re pé, ọtọ ni ohun tí Àlùfáà-ńlá tún wí nígbà tí òun dé ibe. Ó ṣàlàyé pé Àlùfáà-ńlá ni bàbá òun yóò ni owó tabua láìpe, ṣùgbọn owó náà kò ní i ju ọdún méjì lọ tí yóò fi pòórá. Àṣeyìnwá-àṣeyìnbọ owó bàbá Adijatu kò pòórá leyìn ọdún méjì nítorí pé ó maa ń fi owó re ṣàánú àwọn ènìyàn. Ìgbà ti yí padà fún *Madam* Arówólò látàrí ìwà àkọbá ti àwọn ọmọ rẹ̀ hù fún un, tí ó sì fi gbogbo ọrọ̀ àti dúkìà rẹ̀ yáwó ni báǹkì. Gbogbo owó tí ó yá náà ni ó fà á tí wọn fi gbé ese lé dúkìà rẹ̀, nígbà tí kò rí i san. Èyí ló gbe dé ọdọ bàbá Adijatu. Ojú tí *Madam* Arówólò lọjọ náà, kòlè sọro.

Bàbá Adijatu fún un ni mílíọ-nù mewàá láti lọ san gbèsè tó jẹ bánkì, ó sì tún fún un ni mílíọọnù mewàá mìíràn láti fi bere òwò. Omijé ni *Madam* Arówólò fi gba owó náà lọwọ bàbá Adijatu, ó sì túúba.

Ìtakora Ẹ̀sìn Nínú Àwọn Àṣàyàn Fíìmù

Ìtakora Ẹ̀sìn maa ń wáyé látàrí àìgbọraeni yé lórí Ẹ̀sìn, láàrín àwọn elesìn ọtọtọ tàbí ìjọ tí wọn kò jọ ní ìgbàgbọ kan náà láwùjọ. Oríṣiríṣi nǹkan ló ń se okùnfà ìtakora Ẹ̀sìn láwùjọ. Ètò Ìṣèlú jẹ olórí ohun tí ó máa ń sáábà fa ìtakóra Ẹ̀sìn láwùjọ nítori èyí wùn ọ kò wùn mí ló jẹ léyìí tí ó máa ń mú àríyànjiyàn àti ìkùnsínú dáni láàrín àwọn ìjọ kan tàbí òmíràn láwùjọ. Àínítelọrùn, ìbọrù àti àìgbara-enigbọ tún jẹ àwọn nǹkan mìíràn tí ó tún máa ń fa ìtakora Ẹ̀sìn láwùjọ. Àwùjọ tàbí oríle èdè tí ìtakora Ẹ̀sìn bá wà kì í ní ìtesíwájú. Ogun, ìjà, ìpànìyàn, ìjínigbé-bèèrè-owó náà kì í gbeyìn níbọ. Ọ̀rọ̀ Ẹ̀sìn gan-an ló jẹ àwọn òǹkọtàn fíìmù tí a ṣà yàn fún ìwádìí yìí lógún. Wọn ṣe àfihàn èrò wọn nípá Ẹ̀sìn Ìsìláàmù láti jẹ kí àwọn ènìyàn mọ pé Ẹ̀sìn tó rerùn, tí kò fe ire pípa àti àbòsí ni Ẹ̀sìn náà. Èyí yàtọ sí ohun tí àwọn oníjàẸ̀sìn bí, *Boko Haram* tí wọn ń da omi àlááfíà Nàíjíríà ru, ń fe kí a gbàgbọ bí àpeere Nínú fíìmù *Ẹ̀sìn Mi*, gẹ̀gẹ́ bí àpẹẹrẹ, a rí i pé ìtakora wáyé lórí àwọn Ẹ̀sìn ìgbàlódé méjèèjì tí ó wà láwùjọ àwọn òǹkọtàn fíìmù náà. Lọnà àkọkọ, Ẹ̀sìn Ìsìláàmù ni òǹkọtàn fíìmù náà ṣe ègbè láti tako Ẹ̀sìn Ọmọleyìn-Jésù. Ọnà kejì ni pé, òǹkọtàn fíìmù náà jẹ kí á mọ pé Ẹ̀sìn kò fàjà, bí ó ti wù kí ìtakora náà wáyé.

Ìdílé cl1sìn Mùsùlùmí ni wọn ti bí Qudus, kí ó tó takú pé Rọmọlá tí wọn bí ní ilé ti wọn ti yan Ẹ̀sìn Ọmọleyìn-Jésù láàyò, ni òun fẹ́ fẹ́. Èyí dá yánpọn-yánrin sílọ nínú fíìmù *Ẹ̀sìn Mi*. Lọnà àkọkọ, ìwà tí Qudus gbé wọ bí ọwù là á lóòógùn lọdọ ọmọbìnrin Rọmọlá tó yàn láàyò náà. Ẹgbọn Rọmọlá fi yé Qudus pé, Ẹ̀sìn nìkan ló lé fa ìtakora ìfẹ́ láàrín òùn àti . Ẹ wo àyọlò yìí:

Egbon Rọmọlá : In a *nutshell*, torí Rọmọlá le fi wá rí mi?

Qudus: Bee ni, torí re ni. Mo fe jẹ kí e jọọ nítorí Olọrun kí e bá mi bá a sọrọ. *I really like her so much*. Bí e bá lè bá mi bá a sọrọ, inú mi á dùn ju ti eni tí ó gba *Certificate* Àlùjọnnà láti ayé lọ. *She is my dream girl.*

Egbon Rọmọlá : Ẹn en! Mr Qudus!! Wọn ní ọdá tó bá mọ iyì àkókò, kò ní ṣòfò. Ẹ má jẹ kí ń tàn yín, Rọ̀mọ́lá ò lè fe yín.

Qudus: Kín ló dé? Sé ó ti ní ọkọ àfesọnà ni?

Egbon Rọmọlá : Rárá o

Qudus: Kí wá ló dé ti e fi sọ pé, kò lè fe mì?

Egbon Rọmọlá: Torí wí pé ọ ń jẹ "Qudus". Láti *Secondary School* ni mo ti mọ Rọmọlá. Kò lè bá wọn je eran Iléyá.

Qudus: Háà! Eléyií le gan-an ni o. (Ìran 4)

Irú ìhà tí Qudus kọ sí yìí wà lára ohun tó ń ṣe okùnfà ìtakora àti ìjà Ẹ̀sìn . Bí egbọn Rọmọlá ti ṣe akitiyan láti rí i pé òun ṣe Qudus ní etí inú lórí Rọmọlá tó, Qudus takú, ó kọ jálọ pé òun yóò fe Rọmọlá dandan. Ìdí nìyí tí ó fi sọ ara re di òpùro, tí ó wí fún Rọmọlá pé òun kì í ṣe elesìn Ìsìláàmù tàárà. Àkóbá ni èyí gan-an jẹ fún Rọmọlá, nítorí pé ó gba iro tí Qudus pa fún un gbọ. Leyin-ọ-reyìn, ìfe rú bo Rọmọlá lójú, ó mú Qudus lọ sí ọdọ àwọn òbí re, wọn sì gbà á tọwọ tesọ nígbà tí ó fi yé wọn pé òun yóò máa ṣe Ẹ̀sìn Ọmọleyìn-Jésù bí òun bá fe Rọ̀mọ́lá. Ẹjẹ tí Qudus jẹ fún Rọmọlá gan-an ló ṣe okùnfà ìṣòro. Ẹ wo àyọlò yìí

Qudus: Mo mọ wí pé inú re ti dùn nígbà ti mo ti ṣe ohun tí o fe.

Rọmọlá: Láti ọjọ ti mo ti rí e. Ọjọ tí ó ṣe ìrìbọmi ni inú mi dùn jù

Qudus: Màá ṣe gbogbo nǹkan tì ó fe fún ọ. (Ìran 8).

Àyọlò òkè yìí ṣe àfihàn pe Qudus gan-an ló ṣe okùnfà ìṣòro ìtakora Ẹ̀sìn tó wáyé nínú fíìmù *Ẹ̀sìn Mi* yìí. Ìwà ohun-ọwọ-mi-kò-tó-mà-fi-gọgọ-fà-á tí Qudus hù yìí, ní ó bí ìṣòro tí ó kojú lọdọ íyàwó tí ó fe. Yorùbá bọ, wọn ni ohun tí ń wu ọmọ je kì í run ọmọ ninú. Èyí yàtọ si ohun tó ṣẹlẹ̀ sí Qudus nínú fíìmù *Ẹ̀sìn Mi.* Àwọn òǹkọtàn fíìmù tí a ṣà yàn yìí *Semiat* àti *Wòsík*ẹnkẹ, jẹ kí a mọ pé àwọn òbí àwọn ọmọdébìnrin wọnyí (Semiat àti Wosilat) kò náání ìfe tí àwọn ọmọ ní sí eni tí ó wù wọn nítorí pé wọn kì í ṣe elesìn kan náà.

Nínú *Semiat,* bàbá Semiat gan-an ló fa ìtakora Ẹ̀sìn . Yorùbá ní, àáyá tó ni òun yóò tún ojú ọmọ òun ṣe, ó ti èékán bọ ọ. Èyí ló dífá fún bàbá Semiat tí ń dáàbò bo ọmọ re lọdọ àwọn elesìn Ọmọleyìn-Jésù pé kò gbọdọ fe wọn. Àwọn elesìn Ìsìláàmù tí

Semiat pàdé gege bí ọkọ àfesọnà ni ìwà wọn kò jọra. Segun ni Semiat kọkọ yàn láàyò, tí wọn sì nífee ara wọn púpọ, èyí ló mú àwọn méjèèjì lo ète láti pa ìro fún bàbá Semiat pé Ẹ̀sìn Ìsìláàmù ni Segun ń ṣe. Àṣírí iro àwọn méjèèjì padà tú sí bàbá Sọmíàt lọwọ. Ẹ wo àyọlò yìí tí ó hàn nínú ìran karùn ún inú fíìmù *Semiat*:

Segun: *Thank you sir*. Nípa ti àwọn òbí mi, wọn wà ní àlááfíà
Àláájì: Wọn wà láyọ àti àlááfíà. Níbo ni wọn ń gbé àti pé iṣẹ wo ni wọn ńṣe?
Segun: Èkó níbi bàyìí náa ni won ń gbe *Sir*. Òjíṣe Olúwa ni wọn sà.
Àláájì: Òjíṣe Olúwa?
Segun: *Pastor and Pastor (Mrs.)* Olúwọlé Jeremiah Jésùlolúwa
Àláájì: Semiat Olúṣọ Àgùntàn ni o gbé wá ká mi mọlé?*Impossible.*

Ìran 5)

Bàbá Semiat gbàgbọ pé, ẹ̀ṣẹ̀ ni ki ẹlẹ́sìn ọtọọtọ méjí fe ara wọn gege bí tọkọ-taya. Bí bàbá Semiat ṣe fi èrò àti ìgbàgb- re dá ìṣòro àìlọkọ sí ìgbé ayé ọmọ re nìyí. Semiat gbìyànjú láti te bàbá re lọrùn lórí ọrọ Ẹ̀sìn Ìsìláàmù tí ó gbà kanri, ṣùgbọn pàbó ni gbogbo ìgbìyànjú re já sí. Òǹkọtàn fíìmù yìí fi yé wa pé, bí a bá fa gbogbo nǹkan lé Olọrun lọwọ, yóò bá wa tò ó, bí ó ti tọ àti bí ó ti ye. Ní ìkeyìn, Semiat pàde Yusuf tí òun jẹ ẹlẹ́sìn Ìsìláámù lọ́dọ̀ ọ̀rẹ́ rẹ̀ kan, àwọn méjèèjì sì fe ara wọn. Ohun kan pàtàkì tí a fe tọka ní abala yìí ni pé àwọn ọdọ ni ó dàbí eni pé wọn ri Ẹ̀sìn yòówù kí ó jẹ gege bí ohun tí kò ye kí ó di ìfe òtítọ lọwọ nínú ìbáṣepọ ọdá. A lè sọ pé bóyá bí ọrọ Ẹ̀sìn bá di ohun tí a dewọ díọ, tí a kò máa sá sí abe re láti hu ìwà ibi, èké, ìninilára àti ọdájú, àwùjọ wa ì bá túbọ máa gbèèrú sí í.

Àgbálọgbábọ

Bí ọkọ́ bá re òkun, tó re ọsà, yóò padà fàbọ fún Elébùúté. Iṣe ìwádìí yìí ṣe ìṣípayá lóri ìlànà tí àwọn òǹkọtàn fíìmù ajémọ-Ẹ̀sìn Ìsìlàámù ń gbà ṣe àgbékalọ kókó-ìtàn fíìmù wọn. A rí i pé àwọn òǹkọ-tàn fíìmù náa ń wo ṣàkun ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ wọn láti ṣe àtòjọ ìrírí wọn nípa àjọṣepọ̀ òbí àti ọmọ pelú ọ̀rọ̀ìfẹ́ láàrin takọ-tabo. Èyí ló ràn wọn lọwọ láti ṣe àwárí ìmọ tó je mọ Ẹ̀sìn Ìsìláàmù tí wọn ní lọ kàn gan-an. Kò wá sí èyí tó gbé Ẹ̀sìn Ìsìláàmù nìkan rù nínú àwọn òǹkọtàn fíìmù náà, nítorí pé á rí àpeere kókó-ìtàn tó tayọ ọrọ Ẹ̀sìn Ìsìláàmù nínú àwọn fíìmù báà.

Fíìmù wúlò púpọ fún pípolongo Ẹ̀sìn Ìsìláámù nítorí pé ìlànà kíkọni lekọọ ìwà láìfi dandan mú ọmọdé tàbí ọdọ lọ sí M-ṣáláṣí láti lọ gbọ wáàsí ni. Ọpọ ọdọ ni wọn máa ń wà ní ilé-ẹ̀kọ tàbí níbi ìkọṣe, èyí lè má fún wọn ní ààyè tàbí kí wọn nífẹ̀ẹ́ sí líló sí M-ṣáláṣí tàbí ibi wáàsí láti lọ tẹ́tí gbọ́ ọ̀rọ̀ Áláà(*Allah*). Bí àwọn elesìn Mùsùlùmí bá ṣe wáàsí lọnà ọrọ gege bí eré fíìmù báyìí, ọnà kan gbòógì ni ó jẹ fún ìpolongo Ẹ̀sìn Ìsìláàmù. Ìdí ni pé láìkúrò lójú kan, àwọn ọdọ lè wo fíìmù lórí ẹ̀rọ-ìpè lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan tí ọwọ wọn bá dilọ. Èyí ni yóò ṣe okùnfà kí ọkàn wọn fà sí ọrọ Ẹ̀sìn, kí wọn túúbá kúrò nínú àwọn ìwà jàgídíjàgan bí i nàbí ṣíṣe, òògùn owó ṣíṣe, ìjínigbé-gbowó, olè jíjà àti irú àwọn ìwà mìíràn beọ tí ń kojú àwùjọ wa lónìí.

Ìwé Ìtọ́kasí

Abrams, M.H. (1981). *A Glossary of Literary terms*. New York: Holt Rinehart and Winston.

Adágbádá, O. (2010). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá nínú àwọn Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá* pépà kíkà Ọdúnjọ Memorial Lecture.

Adágbádá, O, (2005). *Women Folks in Yorùbá Video Film Industry*. Ph.D Thesis, Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Adédèjì, J.A. (1969). Origin and forms of Yorùbá Masque Theatre 1915- 1945 *Journal of the Historical Society of Nigeria*, 1(4), 387-396.

Adédèjì, J.A. (1981). 'Alárìnjó': The Traditional Yorùbá Travelling Theatre Ògúnbìyí Y. (ed.) *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book,* Lagos. Nigeria Magazine, 22e – 247.

Adéléké, D.A. (1995). Audience *Reception of Yorùbá films, Ìbàdàn as ease study*. Ph.D Thesis, Department of Linguistics and African Languages. University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Adéníyì, T. (2009). *Theatre on Wheels. The Yoruba Travelling Theatre of Nigeria: Its Origin, Organisation and Structure*. Eanada: U-Phemison & Eompany.

Adeyemí, (2006). *Tíọrì Lítírẹ́ṣọ ni Èdè Yorùbá,* Ìjọbú-Òde: Shebíotimọ Publieations Ajíbóyè, O. (2002). *Ìmọ Ìṣọwọlo-Èdè,* Lagos: Tomfetes Publishers Eompany.

Àlàmú, O.O. (1991). *Trends in the development of the Yorùbá film. The first decade (1 9 7 9 - 1 9 8 6)*. An unpublished M.Phil Dissertation, Department of Linguistics and African Languages. University of Ibadan, Ibadan.

Àlàmú, O.O. (2010). Aesthetics *of Yorùbá Film. Lingual-Culture contextual Studies in Ethics Conflicts of the World* (LIEEOSEE). Osaka University, Japan. Research Institute for World Languages.

Akinsola, I. (2024). Theatre-in-Education packages and secondary students' knowledge of Yoruba culture in Ibadan metropolis. *African Journal of Teacher Education*, *13*(3), 169-191.

Akinsola, I.T. (2020a). 'Yorùbá Films in Time Perspective: Past, Present, and Future.' *Yorùbá Studies Review, 5.1.2:277-290*

Akinṣọla, I. T. ati Adeyinka, A. A. (2020). Yorùbá film general preference and secondary

school students' achievement in Yorùbá cultural concepts in Ìbàdàn metropolis. *African Journal of Educational Research* 22.1: 56-69

Adéyínká, A.A. and **Akínsolá, I.T.** (2016). Fíìmù Àgbéléwò Gẹ́gẹ́ bí Ohun-èlò Ìkọ́ni ní Àsà Àti Lítírẹ́ṣọ̀ Alohùn Yorùbá: Fíìmù Arugbá Àti Baṣọ̀run Gáà Gẹ́gẹ́ bí Àwota. In Medubi, D., Gbadebo, D., and Bello, A. (Eds.) *Current Studies in Yorùbá Culture, Language and Literature: A Festschrift for Olugboyega Alaba.* Department of Linguistics, African and Asian Studies, University of Lagos. 564- 582

Babalọlá, S.A. (1966). *The Content and Form of Yorùbá Ìjálá*. Oxford: Clarendon Press.

Bonald de Louis, (1754-1840). "From Theocracy to Sociology: Louis de Bonald and the Reactionary Roots of Social Science". *The International Journal of Interdisciplinary Social Sciences:* Annual Review Press.

Ekwuazi, H.O. (1984). The Film in Nigeria: The Context of Production, Television and Film. Lagos: Bookcraft.

Laurenson, D.T. & Swingewood, A. (1971). *The Sociology of Literature.* USA: MaeGibbon and Kee.

Ògúnṣínà, J.A. (1987). "The Sociology of the Yorúbà Novel": A Study of Isaac Thomas, D.O. Fágúnwà a nd Ọládọjọ Òkédìjì". Ph.D Thesis, Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn.

ÀWỌN ÀTÒJỌ FÍÌMÙ TÍ A GBÉYẸWÒ

1. Wòsíkẹnkẹ
   Láti ọwọ́: Ṣọlá Kòsoko Abínà
   Olùdarí: Segun Ògúngbè
   Ilé-ise tí ó gbé e jáde: *EPSALUM Productions*
   Ọdún tí a gbé e jáde: *2014*

2. Ẹsìn Mi
   Láti ọwọ́: Aishat Lawal
   Olùdarí: Tọpe Adébáyọ
   Ilé-ise tí ó gbé e jáde: *ADEKAZ Productions*
   Ọdún tí a gbé e jáde: *2016*

3. Semiat
   Láti ọwọ́: Bísọlá Abdul
   Olùdarí: Káyọdé Adébáyọ
   Ilé-ise tí ó gbé e jáde: *Koma'a Roll Multimedia*
   Ọdún tí a gbé e jáde: *2017*

4. Adijat Kubura
   Láti ọwọ́: Rónke Odùsányà
   Olùdarí: Abdullahi Abdulrasaq
   Ilé-ise tí ó gbé e jáde: C*orporate Picture Nigeria Ltd,.*
   Ọdún tí a gbé e jáde: *2016*